YORUBA

## ▶ Àwọn ibi ikọwesi to wulo

**Ilé-iṣẹ́ iyilọ si ilu miran**
www.sefor.be
www.dofi.fgov.be

**Idanilohun Lojukanaa (Ilé-iṣẹ́ iyilọ si ilu miran)**
sefor.return@ibz.fgov.be
0032 2 793 82 82

**Fedasil**
(Ilé-iṣẹ́ onidapọ fun awọn ti won wa ibi abo)
www.fedasil.be
0032 800/32 745

**Imọran lori ipada àtinúwá**
www.voluntaryreturn.be
Voluntary return desk:
Chaussée d'Anvers 59a
1000 Brussels

## ▶ Awọn ile-iṣẹ ijọba ni ilẹ ajeji

**Ati wá ibi ikọwesi ile ijọba ilu miran ni ile àjèjì rẹ**
www.diplomatie.belgium.be
0032 2 501 81 11

Responsible publisher: Immigration Office, WTC II, Antwerpsesteenweg 59B - Chaussée d'Anvers 59B, 1000 Brussels

# O ti gba àṣẹ láti kúro ni ilu

Eyi ja si wipe o gbodo kuro ni ilu Beljiomu.

Ki ni nkan deedee la ti ṣe?
Nibo ni o le lọ?
Nibo ni o le ri iranlowo ati imọran?




Ceci est une traduction du Français

ibz Intérieur Binnenlandse Zaken
Cofinanced by the European Return fund
.be

## Nigba wo ni o gbodo kuro ni orilèdè naa?

O gbọdọ ti kuro ni ilu Beljiomu, o pẹ ju, ni ọjọ ti wọn ti kọ si ori àṣẹ lati kuro ni ilu.

## Nibo ni mo le lo?

Oun deedee lati ṣe ti o dee han gedegbe ni ko pada si orile-ede abínibí rẹ. O tun le rin irin ajo lo si orile-ede miran, sugbon o gbodo ni iwe ase ti o fẹṣẹ̀múlẹ̀ lati ṣeyi.

## Nibo ni mo ti le ṣe eto iwe irin ajo?

Ti o ko ba ni awon iwe idanimo lati pada si orilẹ-ede abínibí rẹ, o gbodo lo si ilé-iṣẹ́ ijoba ni ilẹ àjèjì ti orilẹ-ede abínibí rẹ. Ibe ni o ti le gba iwe idanimo lati pada si orilẹ-ede abínibí rẹ. Ti o ba ni isoro lati gba awon iwe irin ajo rẹ, okan ninu awon apá ìsọ ti a ti ko si ipari iwe yi le fun ọ ni iranlowo.

## Ki ni yoo ṣẹlẹ ti mo ba kọ lati kuro ni ilu?

Ti o ba kọ lati kuro ni ilu, awọn ọlọpaa le gbe ọ. Ilé-iṣẹ́ iyilọ si ilu miran le fi ọ pamọ si ihamọ kan tabi aaye ile gbigbe kan ti wọn ti tọju fun iru iṣẹlẹ yi, lakoko iduro fun irin ajo pada si orilẹ-ede abinibi rẹ tabi orilẹ-ede miran ti a yoo ṣe ètò.
Ati pẹlu, ti o ko ba ṣètò lati kuro gege bi àṣẹ ti o gba ti sọ, ó le fa ki a fi ofin de wiwole rẹ. Ifi ofin de wiwọlé rẹ yi tumo si wi pé, fun akoko ọdun mẹta si ọdun mẹjọ, o ko le ni anfani lati gba iwe iwọlu lati rin irin ajo lọ si eyikeyi ninu awon ilẹ orilẹ-ede Yuroopu. A yoo kilọ fun gbogbo orilẹ-ede Yuroopu lati ṣe akiyesi rẹ.

## Bawo ni mo ṣe le sanwo fun irin ajo yi?

O ni lati sanwo fun irin ajo yi fun ara rẹ. Ti o ko ba le ṣeyi, o le tọrọ iranlọwọ lati odo ètò àtinúwá fun ipadabọ. Pelu ètò yi, yoo le gba iwe ipadabo gege bi onírin ajo, enikan ma ba ọ de papa ọkọ ofurufu (ti o ba ma mu ọkọ ofurufu) o de le ri àwọn iranlọwọ miran ati pẹlu.
Ti o ba fẹ jẹ anfani ètò yi tabi o fe gba imọran lori ètò àtinúwá fun ipadabo, gbiyanju lati pe Fedasil lori ago yi 0032 800/32 745. O tun de le pe READ ni adugbo rẹ.

> voluntaryreturn@fedasil.be
> www.voluntaryreturn.be

Ti o ba fẹ kuro layi tọrọ iranlọwọ, o ni lati dágbére fun awọn oṣiṣẹ aláṣẹ Beljiomu. Ọna ti yoo gba lati ṣe yi ni wi pe yoo fun ọlọpa orilẹ-ede ni atọwọda iwe àṣẹ lati kuro ni ilu ti o ba ti sọda eti orilẹ-ede. Ti o ko ba ti sọda eti orilẹ-ede nigba ti o kuro ni Beljiomu, o ni lati fi ẹri ipadabọ ranṣẹ si ori fax (0032 2 274 66 13) tabi si ori email (Bur_sefor@ibz.fgov.be).

## Kini awọn ẹ̀tọ́ mi?

Àwọn ètò lati toro àpètúnpè wa ti o ba gba àṣẹ́ lati kuro ni ilu. A ti ko àwọn ètò yi si isalẹ iwe ipinu. O de le gba imọran lati ọdọ agbejọ́rò rẹ. Ti o ko ba ni agbejoro, o le pe ikan ninu àwọn ilé-iṣẹ́ agbejoro ni adugbo rẹ fun iranlọwọ (lọfẹ).

## Kini o ni lati ṣe?

Di e ninu awọn ètò àpètúnpè le da 'aṣe lati kuro ni ilu' duro. Ti o ba toro àpètúnpè lati da aṣẹ naa duro, fun igba ti a maa duro de idajo, ilé-iṣẹ́ iyilọ si ilu miran le pàṣẹ fun ijọba adugbo rẹ lati fun ọ ni iwe ati duro si ilu fun igba di ẹ (nipa annex 35).
Fun awọn ìyókù, o ko le ri iwe ati duro si ilu gba, o de gbọdọ kuro ni ilu paapa ti o ba ti tọrọ àpètúnpè. Nigba miran, o le má ri aaye lati tọrọ àpètúnpè. A ti ko àwọn ètò yii lokookan si inu 'àṣẹ lati kuro ni ilu' o dẹ ni lati tẹ̀lé wọn.

## Kini awọn ẹ̀tọ́ mi ti mo ba ti ṣe iṣẹ́ lodi?

Ṣe oti ṣe iṣe layi dágbére fun ijọba tabi o ti ṣe iṣe lodi? Ṣe o ti ri àgbákò ni ibi iṣe rẹ? Ṣe ọga rẹ o sanwo fun o tabi owo ọya rẹ ko to € 9.12 fun wakàtí kọọkan?
O yi le ri ẹ̀tọ́ rẹ gba o de le royin àgbákò rẹ fun apá ìsọ ofin ìbójútó awujọ.
Ti ẹri toto ba wa fun iṣe rẹ, apá ìsọ ofin ìbójútó awujo le fun ọ ni iranlọwọ ko ba le ri ẹ̀tọ́ rẹ gba. Apá ìsọ yii naa le fun ọ ni iranlọwọ awọn ètò lati dágbére àgbákò ni ibi iṣe rẹ. O le ri ibi ikọwe si apa iso yii lori website idanilohun ibọlọwọ ewu awujọ fun gbogbo eniyan: www.socialsecurity.fgov.be

YORUBA